مبرة الآل والأصحاب

Ibuseni ni oore fun awon ara ile (Anabi) ati awon Saabe re
Ipele itan nipa awon ara ile (Anabi) ati awon Saabe re

# شذى الياسمين

## في فضائل أمهات المؤمنين

بلغة اليوروبا

# OOrun didun igi ododo ti orewa nipa ajulo awon iya awon olugbagbo ododo


Lati owo
**Ibudo iwadi nipa awon eko esin**
**Eyi T o je aketun fun Ibuseni ni oore nipa awon ara ile (Anabi) ati awon Saabe re.**



**ترجمة: مؤسسة القلم الخيرية العالمية للبحوث والترجمة والتعريب (السودان)**

# Ni oruko Olohun ajoke aiye aske orun

بسم الله الرحمن الرحيم

"النَّبِيُّ أَوْلَى بِالْمُؤْمِنِينَ مِنْ أَنفُسِهِمْ وَأَزْوَاجُهُ أُمَّهَاتُهُمْ"

**(الأحزاب 6)**

**Anabi ni eto si awon oni gbagbo ododo ju ara won lo, atipe awon iyawo re ni awon iya won**

(Suratul- Ahzaab: 6)

## Oro isiwaju
## Alaye soki nipa, awon iya awon olugbagbo ododo

Ope ni fun Olohun, ike ati ola fun eni ti oje opin awon ojise Olohun, ati awon ara ile re, ati awon ijo re, ati awon ti won ba tele won, titi di ojo esan. Leyin naa:

Ipo ti otobi, ati agbega nla nbe fun awon ara ile anabi, lodo awon ti won un tele ilana anabi, ni bamu si awon iwo ti Olohun se lofin fun won, tii se nini ife ati ini akakun won. Eleyi je ona, lati so aso sile ojise olohun, ki ike ati ola ki oma ba: "Mo un fi olohun ran yin leti nipa awon ara ile mi"[1] Awon ti won tele ilana anabi naa, mo owo mo ese kuro lodo awon ti won un koja aala, lati ma gbe apakan ninu awon ara ile anabi tobi koja boseye, gege bi won se mo owo mo ese kuro lodo awon ti won un fi suta kan won, ti won si un korira won.

Awon olugbagbo ododo lapapo, ati awon ti won un tele ilana anabi ladayeri, won un feran awon ara ile anabi, won si un so fifi aburu tabi aida kan gbogbo won di ewo lapapo, papa julo awon iya awon olugbagbo ododo ladayanri. (awon iyawo anabi).

Oje idunu fun ile ise Mabarratul- Aali wal- Ashaahb, lati te iwe yi jade, lati fi kan nipa, okan ninu awon ero ile ise naa, nipa ati se alaye ajulo awon ara ile anabi ati awon ijore, ati lati fi niin ife won rin le, si okan awon olugbagbo ododo, ati lati se atunse awon asigbo nipa won, eyi tin un be lokan apa kan ninu awon Musulumi.

Eyi ni lati se alaye nipa titobi eto awon iya awon olugbagbo ododo, (awon iyawo anabi) ati awon ajulo ti owa fun won, - ki olohun yonu siwon - lati inu al-Qura'n ati sunnah anabi, eyi to un gbe oriyin fun won, gege bi oti se un se alaye agbega ipo won, ati fifi ajulo won han lapapo, mo awon ara ile anabi, bakan naa sise alaye awon iyi ti un be fun won lokokan.

## Akiyesi Pataki:

[1] Sahihi Muslim: ounka ahdith, (8042).

Olohun Oba so pe: “Anabi ni eto si awon oni gbagbo ododo ju ara won lo, atipe awon iyawo re ni awon iya won” (Suratul- Ahzaab: 6).

Eyi ni pe Awon iyawo anabi je iya fun olugbagbo ododo, gege bi anabi naa se jee baba fun won,[1] ti awon Muhaajiriina ati ansaar si je awon omo iya esin fun won, Awon ti won un se adua fun bayi pe: “Olohun wa forijin wa ati awon omo iya wa ti won ti gba iwaju wa pelu igbagbo odoo” (Suratul- Hashri: 10).

Enikeni toba bu enu ate lu okan ninu awon iyawo anabi, oluware ti jade kuro ninu ogba igbagbo, nitori wipe tobaje olugbagbo ododo ni, koni sebee, tori wipe omo ko gbodo bu enu ate luu iya re.

Ije iya awon iyawo anabi fun awon Musulumi oda gege bi olu bini gangan ni, latari awon ohun ti oso po mo ninu apanle, igbe eni tobi, ati ifi ebi eni se iyanran.

Nje awon iya kan wa bi, ti won ni apanle ju awon obinrin ti olohun sa lesa fun ojise re lo, lati fi won se aya? Olohu so pe: “Ire ko ni eto lati fe awon obinrin miran leyin awon eyi, tabi ki ofi awon iyawo miran paro won, bi oti wu ki ewa won wu o to, afi awon ti owo otun re ni (ni ikologun). Atipe Olhun je oluso lori gbogbo un kan” (Suratul- Ahzaab: 52).

Gegebi olohun tun se so nipa Zainab bint Jahash bayi pe: “Nigba ti Zaidu ti pari bukata re ni odo re, A see ni iyawo fun o, nitoripe ki oma ba je laifi, fun awon olugbagbo ododo, nipa fife iyawo omo ti won npe mo ara won (ti oti koo sile) ni gba ti oba ti pari bukata tie pelu re, ase Olhun je ohun ti oni lati se” (Suratul- Ahzaab: 37).

Olohun si tun se alaye wipe won ni ola ju awon obinrin gbogbo agbaiye lo: “eyin iyawo anabi, eyin ko da bi awon obinrin miran, ti eyin ba npaya Olohun” (Suratul- Ahzaab: 32).

---

[1] Eyi ni ije baba ti itumo, ni tori oro Anabi ti oso bayi pe: (Dajudaju emi wa ni ipo baba fun yin), Abu Daud ni ogba wa, tira ti imora, apa oro kiko ida oju ko gabasi ni igba ti aba un biya bukata, ounka (8) Imam Al-Albaani so pe, ahdith naa da.

Bakan naa ni olohun oba se ni ewo lori awon olugbagbo ododo, lati fe won, gege bi oti se se ni ewo lori omo, lati fe iya re, bi o ti le je wipe eto ni lati fe awon obinrin miran ti o yato si won. Olhun so pe: “ko to fun yin ki ese ohun ti yio je inira fun ojise Olohun, atipe eko gbodo fe awon iyawo re leyin re lailai, dajudaju eyi je nkan ti o tobi lodo Olhun” (Suratul- Ahzaab: 53).

Latari idi eyi, anabi ama kedun fun gbogbo ohun to bale je ifi aburu kan awon iyawo re, ninu oro tabi ise, eyi loje ki olohun pa awon olugbagbo ododo lase, wipe won ko gbodo ba won soro, lai si igaga:“Atipe nigbati eba fe toro nkan lowo won, (awon iyawo anabi) ebere lowo won leyin gaga, eyi je afomo julo fun okan yin, ati fun okan awon naa, ko to fun yin ki ese ohun ti yio je inira fun ojise Olohun” (Suratul- Ahzaab: 53).

Eyi fi ye wa pe, ko ni eto rara lati mo bu enu ate lu won, tabi lati mo bu won,  tabi lati mo fi ohun ti ko leto royin won, olohun oba so pe: “Ire anabi so fun awon iyawo re, ati awon omo obinrin re, ati awon obinrin awon olugbgbo ododo pe, ki won je kii awon aso jalabu won ma bale, eyi ni odara lati le fi mo won yato, ki won mo ba ma yo won lenu, Olohun je Alaforijin Oni ike” (Suratul-Ahzaab: 59).

Leyin naa Olohun tun so pe: “Bi awon alagabagebe ko ba si wo ninu iwa buburu won, ati awon eni ti arun npe ninu okan won, ati awon oluda idagiri sile ni ilu Madina, (nipa iroyin iro) dajudaju A o de o si won, (A o si fun o lagbara lori won) leyin naa won ko nile ba o se aladugbo po ninu re, ayafi fun igba die” (Suratul-Ahzaab: 60).

Eleyi ni, lati fi se itoka, losi bi oun ti awon eniyan, ti enu bole so, nipa bi anabi se fi Zainab se aya, leyin ti oti je iyawo fun Zaid, eyi ti anabi yan lomo, gege bi olohun se se alaye eleyi ninu ogba oro (Suratul- Ahzaab), ese (37), eyi lofi un je wipe, olohun se isoro anabi ati awon iyawo re laida, ni okan ninu iwa awon alagabagebe (Munafiq), osi un kii awon Muhumini ni ilo wipe ki won mo se da bi won.

Olohun Oba situn se alaye ninu ogba oro naa, (Suratul-Ahzaab), wipe ohun koni gba, awi jare eni yio wu, ti  ko ba ronupiwada, ti owa ku sori bibu enu ate lu awon iyawo anabi, leni ti

o ko eyin re si al-quran at sunnah Anabi, ti o wa un tele oro awon asiwaju, ati awon olori, Olohun sope: “ojo ti A o mayi oju won pada ninu ina,won yio maa sope, omase lara wa o, kobaje pe ati tele ti Olohun ati ojise naa. Won yi o sit un so pe, Olohun wa dajudaju awa ti tele ti awon asiwaju wa, ati awon agbaagba wa, nitorina won si si wa lona, kuro ni oju ona ti oto” (Suratul- Ahzaab: 66-67).

Ni ti tori idi eyi, nje ibu enu atelu awon iyawo anabi, un be ninu oro ire bi, tabi oro buruku?

Iwo naa yaa aworan sinu lakare re pe, oun buu A’aisha tabi Ahfsah, ti owa boju wo eyin, ti ori anabi ti un wo ho, ti un si ngbo oro re, bawo ni ise si re oba seri nigba naa, bawo si ni ose fe ki anabi naa se si o.

# Awon iyawo anabi ni ola julo lori gbogbo awon obinrin agba nla aiye

Olohun sope: “eyin iyawo anabi, eyin ko da bi awon obinrin miran, ti eyin ba npaya Olohun” (Suratul- Ahzaab: 32).

Eyi tumo sipe: Kosi obinrin kankan, to ni ola ju yin lo, nitori iberu olohun oba yin, iberu olohun yii, ni ajulo won fi ju gbogbo awon obinrin ti oku lo, ni igba gbogbo, laisi ayafi rara, eyi koti poju lati fi rin le, fun awon iyawo, eni ti oni ola julo laarin awon anabi, ati awon ojise, ati awon eda lapapo, koti poju lati fi rin le bakan naa, fun awon obinrin ti ose wipe, olohun ati ojise re, sa won lesa, awon naa si sa olohun ati ojise re lesa.

Lododo ni iberu olohun rin le fun won, pelu oro olohun, nitori pe won sa olohun ati ojise re lesa, atipe won gbe ajulo fun ile ikeyin, lori ile aiye ati oso re, leyin ti ese oro ifun won lesa sa sokale, olohun so wipe: “Ire Anabi so fun awon iyawo re pe, ti eyin baje eni ti un fe igbesi aiye ati oso re, ewa nibi ki emi fun yin ni ipese, ki un si fi yin sile, ni fifi sile ni irowo- irose. Sugbon bi eyin baje eni ti un fe, ti Olohun ati Ojise re ati ile ikeyin (Orun), dajudaju Olohun ti pese esan, ti otobi sile de, awon oluse rere lobinrin ninu yin” (Suratul- Ahzaab: 28-29).

Won sa Olohun ati ojise re lesa, ati ile ikeyin, won gbe ile aiye, oso ati igbadun ibe ju si le,  ohun ti won se yii je ododo, nitori pe kosi ohun oro aiye tole je, ki won seku pelu anabi, tabi tole je, ki won se suru lori awon ilekoko igbesi aiye pelu anabi, ayafi ododo igbagbo ati iberu olohun, latari idi eyi, ni olohun naa fi gba won leru, osi se apanle won, Olohun sope: “Ire ko ni eto lati fe awon obinrin miran leyin awon eyi, tabi ki ofi awon iyawo miran paro won, bi oti wu ki ewa won wu o to, afi awon ti owo otun re ni (ni ikologun). Atipe Olhun je oluso lori gbogbo un kan” (Suratul- Ahzaab:52)

Apanle Olohun yii fun won pin si abala meji:

1- Olohun ko fun anabi re, wipe ko gbodo fe, obinrin miran le won.
2- Olohun ko fun anabi re, wipe ko gbodo ko, eni kankan won sile rara, lati fe elomiran paro won, latari ki won leje iyawo fun titi lai lai, ni ile aiye ati lorun.

Eyi ni Olohun fi ko fun awon olugbagbo ododo, wipe won ko gbodo fi won se aya leyin anabi, Olohun so pe: “ko to fun yin ki ese ohun ti yio je inira fun ojise Olohun, atipe eko gbodo fe awon iyawo re leyin re lailai, dajudaju eyi je nkan ti o tobi lodo Olhun” (Suratul- Ahzaab: 53).

Gege bi olohun se fi won si ipo iya, fun gbogbo olugbagbo ododo, Olohun so wipe: “Anabi ni eto si awon oni gbagbo ododo ju ara won lo, atipe awon iyawo re ni awon iya won, atipe awon ebi, apakan won ni eto si ara won, (nipa ogun jije) ninu ako si le Olohun, ju awon onigbagbo ododo, ati awon ti won se hijrah lo, ayafi ti e ba fe se rere, si awon ore yin, bayi ni eyi je akosile ninu tira Olohun”. (Suratul- Ahzaab: 6).

Eto ni fun gbogbo oni laakare, lati ronu si awon akiyesi yi daadaa, nipa apanle towa fun, awon iya awon olugbagbo ododo, ki iyonu Olohun mo ba won.

## Ariwo se oye ti o wa nibi pipo awon iyawo anabi

Anabi je awo kose rere fun gbogbo awon olugbagbo ododo gege bi Olohun Oba se so pe: “Dajudaju ikose rere un be fun yin, lara Ojise Olohun, fun eni ti o un beru Olohun, ati ojo ikeyin, ti o si un ranti Olohun ni opolopo” (Suratul- Ahzaab: 21). Awon ise re sije orisun kan ninu awon orisun ofin esin.

* Eyi ni osodi Pataki, lati ri awon ti yio ma gbe awon ofin naa jade, lati inu ile anabi, papa julo awon idajo, ti oso po mo oro ebi, oro oko ati aya, ati awon idajo, ti odawa fun awon obinrin onigbagbo ododo ni kan, ni akoko won, ati awon akoko miran leyin won, awon iyawo anabi, ni won un gbe, awon idajo yii, lo si odo awon obinrin Musulumi bii won.

* Idi miran nipe, eko esin ti anabi fi un ko, awon iyawo re, yio je ki won je awo kose rere, fun awon olugbagbo ododo lobinrin, ni gbogbo igba, eyi siti sele bee. Awon iyawo anabi naa je, awo kose rere, fun gbogbo olugbagbo ododo lobinrin, eyii naa je okan, ninu awon idi ti iyawo anabi fi po, apere fun eyi nii, asiwaju lobinrin A’aisha, eyi ti oje okan, ninu awon ti ogba, adith ti opo ju wa, lati odo anabi.

* Idi miran nipe, nigba ti esin Islam sese bere, ose pataki lati ni, asopo laarin awon iran larubawa, ati awon eya eya won, latari ki ipepe si esin, le rorun, apejuwe fun eyi ni, bi anabi se fi Juwairiya se aya, ti eyi si je, idi ti gbogbo awon banil- Mustalaq fi gba esin Islam.

* Idi miran nipe, lati je ki asopo ti ogban un gban, lewa larin anabi, ati awon ijo re, ati lati fi se apanle won, ati lati fi gbe iyi fun won, apejuwe fun eyi ni, fifi ti anabi fi A’isha ati Ahfsah se aya, gege bi oti se fi, awon omo re lobirin fun, Uthman at Alli, ki Olohun yonu si gbogbo won lapapo.

* Idi miran nipe, fife apakan ninu awon iyawo re, je sise alaye idajo ofin esin, eyi ti koje mimon tele, gege bi ai koni eto lati pe, omo agbato ni omo eni, eyi ni ofaa, ti anabi fife Zainab bint Jahsh, leyin ti Zaid ibn Ahrithah, ti ko sile tan, eyi ti won un pe ni, omo anabi.

Idi miran nipe, lati se ikun lowo fun apakan won, latari ile koko isemi, ati ikedun, fun idamu ti oba won, apejuwe eyi ni, fife Saodat bint Zamu’ah, eyi ti oko re ku, ati Ummu Salamh, eni ti oko re ku si oju ogun, ti osi fi awon omo orukan si le, bakan naa, fifi Ummu Ahbibah se aya, eyi ti oko re, koomon kuro ninu esin Islam, ni orile ede Ahbasha, ti osi wa ni ohun ni kan, fifi gbogbo won se aya lodo anabi, un je ikun lowo fun won, ki Olohun yonu si won lapapo.

Ti obaje wipe, fifi won se aya yi, baje titori igbadun obinrin nikan ni, anabi oba ti wa pelu iyawo kan fun odun medogbon, (25), to un ti wipe, iyawo naa si fi odun medogun juulo,(15) nigba ti anabi si un be ni odo langba, bakan naa, gbogbo awon iyawo re, oba si je windia omoge, sugbon riri windia kan soso laarin won, ohun naa ni A’aisha, nigbati awon ti oku si je adelebo tabi opo, ti won je oni omo wewe, eyi je eri wipe, kii se ni tori igbadun obinrin ni oje kofi won se aya.

# Awon iboju wo ti okari nipa awon iya awon olugbagbo ododo

Gbogbo awon iyawo anabi, ni ofi si aiye lo, ayafi Khadijah ati Zainab bint Khuzaimah, awon mejeji ku loju aiye anabi.

Gbogbo won pata, ni won si sin si baqihi, ayafi Khadijah, eyi ti won sin si Ahjun ni Makkah, ati Maymunat, eyi ti won sin si saraf, (aye) ti o summon tanihim, gege bi aso sile re, ni aye ibi ti, anabi ti koko wole too gangan, gege bi iyawo.

Awon mewa ninu won, ni iran won papo mo anabi, ni idile baba re, awon naa ree: Ummu Ahbibah, Khadjah, Ummu Salamh, A'aisha, Ahfsah, Saodah, Zainab bint Jahash, Juwairiyah, Zainab bint Khuzaimah, ati Maimunah, bakan naa ni, iran Zainab bint Jahash tun papo mo anabi, ni idile baba ati iya re, iya re ni, Umaima bint Abudul Mutalib, aburo baba anabi lobinrin, gege bi oti se ba anabi pade, ni idile baba re, lodo Khuzamah bin Mudrikah bin Iliyas.

Anabi tun awon iyawo re meji, fun ni oruko, leyin ti won ti un je Barrah tele, oso won ni Maimunah, ati Juwairiyah.

Zainab bint Khuziamah, Safiyyah, Maimunah, Khadjah, ki olohun yonu si won lapapo, won ti fe oko meji meji, ki anabi to fe won, nigba ti oja si wipe, A'aisha ni kan ni omoge, ninu gbogbo won, ki Olohun yonu si won lapapo.

## Awon ajulo ti okari laarin awon iya awon olugbagbo ododo:

1. Gbogbo won ni won je iyawo fun anabi, laiye nbi ati lorun.
2. Mimon awon ara ile anabi, kuro nibi ebo, esu, awon ise buruku, ati awon iwa iye pere, gbogbo awon iyawo re naa, si un be ninu awon ara ile re. Olohun Oba sope: "eyin iyawo anabi, eyin ko da bi awon obinrin miran, ti eyin ba un paya Olohun, ki ema se ohun ni ririo, (pelu awon okunrin miran), ki eni ti arun wa ninu okan re, ma ni ireti (si yin), atipe ki esi ma so oro ti odara. Atipe ki e gbe inu ile yin, ki ema se fi ewa yin han sita, gege bi fifi han, ti awon alaimokan ti akoko, ki esi ma gbe irun duro, ki esi

ma yo Zakat, ki esi tele ti Olohun ati Ojise re, dajudaju, Olohun gbero lati mu, iwa ti ko mo kuro fun yin, eyin ara ile, atipe ki o le so yin di eni mimo. Atipe ki eyin se iranti, ohun ti won un ka, ninu awon aayah Olohun, ninu ile yin, ati ogbon, dajudaju Olohun je Alaanu ti O si mo gbogbo un kan" (Suratul- Ahzaab: 32-34). Eri yi ko awon iyawo anabi naa sinu, nitori pe nipa won ni ofi sokale.

3. Olohun fi gbogbo won si, ipo iya fun awon olugbagbo ododo, ni abala apanle ati ibowo fun ni. Olohun so pe: "Anabi ni eto si awon oni gbagbo ododo ju ara won lo, atipe awon iyawo re ni awon iya won. (Suratul- Ahzaab: 6).

4. Won gbe ajulo fun, isa Olohun ati Ojise re, ati ile ikan yin lesa, lori ile aiye, ati oso re, Olohun si fi laada ti opo san won ni esan, Olohun so pe: "Ire Anabi so fun awon iyawo re pe, ti eyin baje eni ti un fe igbesi aiye ati oso re, ewa nibi ki emi fun yin ni ipese, ki un si fi yin sile, ni fifi sile ni irowo- irose. Sugbon bi eyin baje eni ti un fe, ti Olohun ati Ojise re ati ile ikeyin (Orun), dajudaju Olohun ti pese esan, ti otobi sile de, awon oluse rere lobinrin ninu yin" (Suratul- Ahzaab: 28-29). osi ti je mimo wipe, won sa Olohun ati Ojise re lesa, idi re ti won fi wa pelu anabi.

5. Olohun fun won ni, ilopo laada, lori ijosin ati ise rere won, Olohun so pe: "Eni ti oba tele, ti Olohun ati Ojise re, ninu yin, ti osi un se ise rere, A o fun ni esan re ni ilopo meji, A o si tun pese jije mimu ti oni aponle fun" (Suratul- Ahzaab: 31).

6. Kosi obinrin kan kan, ti oda bi won, nipa agbega ipo ati ola, Olohun so pe: "eyin iyawo anabi, eyin ko da bi awon obinrin miran, ti eyin ba un paya Olohun, ki ema se ohun ni ririo, (pelu awon okunrin miran), ki eni ti arun wa ninu okan re, ma ni ireti (si yin), atipe ki esi ma so oro ti odara. (Suratul- Ahzaab: 32).

7. Olohun gbe won ga nipo, latari kika oro Olohu ati oro Ojise re, ninu ile won, Olohun so pe: Atipe ki eyin se iranti, ohun ti won un ka, ninu awon aayah Olohun, ninu ile yin, ati ogbon, dajudaju Olohun je Alaanu ti O si mo gbogbo un kan" (Suratul- Ahzaab: 34).

# Awon ajulo adayanri fun okookan ninu awon iyawo Anabi

## Iya awon olugbagbo ododo Khadija bint Khuwylid ki Olohun yonu sii:

### 1) Khadija bintu Khuwaylid:

Oruko re ni, Khadija bintu Khuwaylid, bin Asad bin Abdl-Uzzah bin Qussayi, Qussayi je Baba-baba anabi, Ohun ni enikeji ti osun mo Anabi ju, ni idile baba, ninu awon iya awon olugbagbo ododo, Anabi ko fe, eni kakan miran, ninu awon iyawo re, ninu aromodomo Qusayi, ayafi Ummu Habiba bint Abi-sufyaan.[1]

Khadija je obinrin, ti o Pataki ju lo, ninu gbogbo awon obinrin iran quraish, ohun ni osi tobi ju ni iran, ohun naa si ni owo re si tun po ju ninu won, Ojise Olohun je, omo odun meedogban ni igba ti o fee, leyin oko re ti o un je Abi Haala bin Annabaash bin Zuraara Al-Ttamimi, alajose awon ebi Abud-Daar.

Ogba Ojise Olohun gbo, o si ran lowo, eyi ni Anabi fi un gbe ola fun, lori gbogbo awon obinrin,[2] Ohun nikan ni o bi awon omo Anabi, ayafi Ibraheem, ti o je omo erubinrin Maariya, Ojise Olohun ko fe iyawo le, ti o fi ku, ni igba ti Hijra ku odun meta.

### Ninu awon aponle re:

1. Owa ninu awon, ti won koko gba iwaju, lati gba esin-Islam: Ohun ni okoko ni igbagbo si, ohun ti Olohun so kale, yio si mo ri, esan igbagbo re, ati esan awon ti won tun gbagbo leyin re.[3]

---

[1] Ummu Ahbibat pade pelu Ojise Olohun, lodo baba baba A'bud Manafi bin Qusayi, Khadijat naa si pade pelu Ojise Olohun, lodo baba baba Qusayi, sugbon gbogbo awon iyawo Ojise Olohun ti oku ba Anabi pade, lodo awon baba baba ti won ju Qusayi lo, (Murrat, Kaa'b, Luayi, Khuzymat, Ilyaas ati Mudar.

[2] Itumo ni pe, lori gbogbo awon obinrin ni akoko re, oje okan ninu awon asiwaju obinrin agbaye merin, awon naa ni: Aasiyat bint Muzahim iyawo Fria'wn, Maryam ibnat Imraan, Khadijat, ati Faatimat, ki Olohun yonu si won lapapo.

[3] Nitori pe ohun ni akoko, eni ti okoko gba, esin Islam, ninu awon obinrin. Eni keni ti o ba la ona dada, yio maari esan re, ati esan gbogbo, eni ti o ba too ona naa. Eni ti o toka rere fun eni, oda bi eni ti ose rere naa gan ni, labala laada. Eni ti o ba pe eni, losi ibi imona, yio maari irufe esan, gbogbo awon ti won ba tele, ti ko si ni bu esan won ku rara. (lo wo alaye ekunrere ninu Fatihul-Baary, apa oro nipa awon ajulo Khadijat, bakan naa, lo wo Niahyatul-hijaaz fi syrat saakinil- hijaaz, ti Al-tahtawy, ati sharihu Al-Nawawy a'la sahihi Muslim.

2. Ojise Olohun ko fe, iyawo Kankan miran le, titi ti o fifi aiye sile, odawa pelu Anabi, fun odun meedogbon, ninu isemi loko laya re, tii se odun mejidinlogoji.

3. Ife re je arisiki, fun Ojise Olohun, lati odo Olohun, ife re si je ajulo.[1]

4. Anabi mo un ranti re pupo, o si mo un yin, asi mo ro awon ti Khadijah un fe po.

   A'aisha so wipe: "Mi o jowu obinrin kankan, ninu awon iyawo Anabi, to bi mo se jowu Khadijah, fun bi Anabi se mo un paara oruko re, mi o si fi oju kan rara.[2]

5. Ohun ni eni ti o dara ju, ninu awon obinrin ijo Anobi Muhammad. Imam Bukhari gba oro wa, lati odo Alli bin Abi Taalib, ki Olohun yonu sii, ti o so bayi pe: "mo gbo Ojise Olohun, ti o un so bayi pe: Obinrin ti o dara ju ni Maryam, obinrin ti o si dara ju ninu ijo ohun ni Khadija".[3]

6. Olohun se Ola fun, osi fun ni iro idun nu, ile kan ninu al-jannah, lati ara igi qasab, eyi ti ko ni ariwo ti ko si ni waala.

   Imam Bukhari ati Musulumi gba oro wa, lati odo Abu Hurayrah, ti o so bayi pe : "Jibreel wa si odo Anabi, osi so wipe: Ire Ojise Olohun Khadija ree o, ti ogbe  igba lowo, ti obe wa ninu re, abi ounje abi mimu, ti oba ti de odo re, so fun pe Olohun oba re un ki o, emi naa si un ki, ki osi fun ni, iro idunnu ile kan, ninu al-jannah lati ara igi qasab, eyi ti ko ni ariwo ti ko si ni waala".[4]

7. Olohun fun Anabi ni awon omo lati ara re, eyi ti ko fun, lati ara awon iyawo miran.

---

[1] Sahihi Muslim, ounka ahdith re ni, (5342). Ninu ahdith naa Ojise Olohun so pe: "Dajudaju won fi ife re, se ije imu fun mi (arisiki), iwo naa ronu bi ife re, se je ije imu fun anabi, lati odo Olohun.

[2] Sahihi Muslim, ounka ahdith re ni, (5342).

[3] Sahihi Al-Bukhary: ounka hadith ni, (3815).

[4] Sahihi Al-Bukhary: ounka hadith ni, (3820).

Ojise Olohun so bayi pe: “Olohun pese omo fun mi lati ara re, eyi ti ko wa si aiye, lati ara awon iyawo ti o ku”.[1]

## 2) Saudat bint Zamua’h ki:

Iya awon olugbagbo ododo Saudat bint Zamua’h ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni, Sauda bint zamua’h, bin Qais bin shams bin abdu wuddi, bin Nasir bin Malik bin Hisli bin A’amir, bin Luay bin Ghalib bin Fihr. Oruko iya re ni, Al-Shamus bint Zaid bin A’mur, ara idile Ansaar.

Ki oto fe Anabi, o ti koko fe Sukraan bin A’mur, O gba hadith wa, lati odo Anabi, lati odo ti re naa, Ibn Abaas, ati Yahya bin Abdullah bin Abdurrahman bin Sa’d bin Zuroro, si gba hadith wa, Oti gba esin Islam, ni ibere pepe, ni ilu Makkah, osi se hijirah elekeji pelu oko re, lo si Habasha, ibe naa si ni oko re ku si.[2] Ohun ni akoko obinrin ti, Anabi fe leyin iku iya wa Khadija, ni ilu Makka, Ohun nikan losi un be, pelu Anabi fun odidi odun merin, O je asiwaju lobinrin, osi je alaponle abiyi. Oku ni ipari akoko Khalifa U’mar bin Khataab, ki Olohun yonu sii.

**Ninu awon aponle re:**

1- Itara re, lati mo be ni abe ase Anabi, eyi ni omuu fun iya wa A’aisha, ni ojo ipin orun re, lati le si mo bee, ni iyawo lodo Anabi, ni aiye ati ni orun ninu ali- jannah.

   Ibn Sa’d toka si, oro Saudah ninu tira Tabaqaat, ti oso bayi wipe: “Sauda so fun Anabi bayi pe: “Mo fi Olohun be iwo Anabi, ki un si mo wa pelu re, bi o ti le je wipe, mi o ni bukata si okunrin mo, sugbon mo fe, ki won gbe mi dide, ni ojo igbe nde, pelu awon iyawo re, Anabi si gba lati se bee”[3]. Bakan naa ni, Imam Bukhari gba oro wa, lati odo A’aisha ti oso bayi pe: “Sauda bint Zamua’h obun A’aisha ni ojo orun re, Anabi amoo pa ojo orun Saudah po mo ti A’aisha”.[4]

---

[1] Imam Tabaraany gba wa ninu tira al-mua’jam al-kabir, ounka hadith ni, (22), baab dhkiri azwaaji Rasul Allah, waminhunna Khadijat bint Khuwaylid, part (23) oju ewe (13).

[2] Tahdhiib al-ttahdhiib, ti ibn Ahjar Al-A’sqalaany, (12\ 455).

[3] Pelu ayi pada lati inu tabaqaat ibn sa’d (8\ 45).

[4] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith ni (5212).

2- A’aisha mo un fe ki ohun dabi re: Imam Muslim gba hadith wa, lati odo A’aisha ti oso wipe: “Mi ko ti ri obinrin kan, ti mo un feran kin da bii re,[1] ju Sauda omo Zama’h.[2]

### 3) A’aisha bint Abu Bakir Al-Siddiq:

Iya awon olugbagbo ododo A’aisha bint Abu Bakir Al-Siddiq ki Oluhn yonu sii:

Oruko ni A’isha bint Abu Bakr Al-siddiq, eyi ti oruko re un je, Abdullah bin Uthman ara iran al- ttaymi, ni idile Quraishi, adape A’aisha ni Ummu Abdullah, O be Anabi pe, ohun fe adape oruko kan, Anabi wa so fun wipe: “Maa je adape, oruko omo okunrin, omo iya re obinrin” eyi tii se (Asmohu) won wa un daa pe ni, Ummu Abdullah, eyi ti o je, Abdullah bin Zubair bin Al-A’waam, ati Asmahu bint Abi Bakr. Iya re un je Ummu Ruumaan bint Uwaymir Al-kinaaniyat, won bi iya wa A’isha ni, odun kerin, leyin ti Olohun gbe Anabi dide ni Ojise, Anabi si fee ni omo odun mefa, osi wole too loko laya, ni omo odun mesan, ko si fe omo ge Kankan ti oyato sii, afomo re sokale lati sanma, ati wipe leyin Khadija, ohun ni eni ti Anabi ni ife si julo, ninu awon iyawo re, ohun ni o ni agboye esin julo, ninu awon obinrin, ti opolopo awon saahaba un gba idajo esin lodo re.[3]

Ni igba ti Anabi ku, o je omo odun mejidinlogun, (18) o si ku, ni ojo ketadinlogun, (17) ninu osu Ramadan, ni odun karundinlogota Hijra, Abu Huraira ni, o ki irun si lara, ti won si sin si Al-baqi’.

### Ninu awon aponle re:

1- O je iyawo ti Anabi ni ife si julo, leyin iya wa Khadijat, ki Olohun yonu sii.

Imam Al- Bukhary gba oro wa, Lati odo A’Mur bin Al-A’as, ki Olohun yonu sii, wipe Anabi fi ohun se, adari ogun Dhaat al-

---

[1] Sahihi Muslim, ounka ahdith ni (1463).

[2] Itunmo ni pe mo fe kin da bi re nibi gbogbo un kan.

[3] Lowo ohun ti A’aishah gba wa, ninu ohun ti ofi se alaye, lori oro awon saabe titi Badru-Deen al-zarkashy.

SSlaasil, oso wipe: mo wa de odo re, mo wa so wipe, tani eni ti o ni ife si ju? O so wipe: A’aishat, mo so wipe: tani ninu awon okunrin? O wipe baba re…”.[1]

2- Malaika Jibril ki Olohun ke, ofi aworan A’isha han, ojise Olohun ninu egige aso ariiri, ki o to fe.

Imam Al- Bukhary ati Muslim gba egba wa, lati odo A’isha oso wipe: “Ojise Olohun so wipe: Malaika fi o han mi, ni oju orun, ni ee meta, ninu irepe aso ariiri, o si so wipe: Iyawo re ree, mo ka aso kuro ni oju re, mo wa ri wipe iwo nii, mo wa so wipe, ti eyi ba je lati odo Olohun, ki Olohun muu se.[2]

3- Malaika Jibril ran, Anabi si pe ohun salama sii.

Imam Bukhari gba oro wa, lati odo A’aishat pe: “A’isha so wipe: Ni ojo kan, Ojise Olohun so wipe: Ire A’isha, Malaika Jibril un salama si o, mo wa so pe: Ki ike ati ola Olohun ati alubarika re, ko maa baa ohun naa. Iwo un ri ohun ti emi kori”.[3] (Anabi ni ogba lero).

4- Olohun maa un so (waayii) kale, fun ojise re, lori ibusun A’isha, eyi ti ko sele, lodo awon iya awon olugbagbo ododo kankan.

Ojise Olohun so wipe: “Ire Ummu Salama, ma ti ara A’isha se mi, nitori pe mo fi Olohun bura, (waayii) oso kale funmi, lori ibusun eni kan kan yin, ayafi A’isha ni kan”[4]

5- Ohun ni eni ti, Anabi koko beere, isa esa lodo re, leyin ti aayah ifun ni, ni esa sokale tan, ninu oro Olohun ti o so bayi pe: “Ire Anabi so fun awon iyawo re pe, ti eyin baje eni ti un fe igbesi aiye ati oso re, ewa nibi ki emi fun yin ni ipese, ki un si fi yin sile, ni fifi sile ni irowo- irose. Sugbon bi eyin baje eni ti un fe, ti Olohun ati Ojise re ati ile ikeyin (Orun), dajudaju Olohun ti pese esan, ti otobi

---

[1] Sahihi Al-Bukhary: ounka hadith ni, (4358).

[2] Sahihi Muslim, ounka ahdith je (2438).

[3] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (8673).

[4] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (3775).

sile de, awon oluse rere lobinrin ninu yin”. (Suratul- Ahzaab: 28-29).

Anabi si so fun lati gba, imoran awon obi re, Osi se esa Anabi, si waju gbigba imoran lodo awon obi re, awon Iya awon Olugbagbo ododo, toku naa sii tele ojupon na re.

Imam al- Bukhari ati Muslim gba egba wa, lati odo A’isha oso wipe: “...kin ni yio tun mumi, sese logba ase, lodo awon obi mi, lori oro yii? Moni ife si Olohun ati ojise re, ati ile-ike yin, osi so wipe: awon iyawo ojise Olohun, ti oku naa, tele nkan ti mo se”.[1]

6- Awon aaya al-Quran kan sokale, ni ti tori re, ninu re ni, eyi ti oso nipa re gan gan, ati eyi ti oso nipa gbogbo ijo Musulumi lapapo. Ninu eyi ti o je adayanri fun: Nipe Olohun oba se afo mo re, kuro nibi iro nla ti won pa mo. Olohun so pe: “Dajudaju awon eni ti won wa, pelu adapa iro, je ijo kan ninu yin, E ma se ro pe iro naa je, buburu fun yin, oro ko je bee, rere ni fun yin, olukuluku ninu won ni ere ise ese re, yio ma be fun, atipe eni ti o ba se, eyi ti opoju ninu re, ninu won, iya ti otobi un be fun”. (Suratu Nuur: 11) . Titi de ibi oro Olohun ti oso pe: “Awon onibaje ni obinrin, ni oto fun awon onibaje okunrin, atipe awon onibaje ni okunrin, ni oto fun awon onibaje obinrin, atipe awon obinrin rere, ni odara fun awon okunrin rere, atipe awon okunrin rere, ni odara fun awon obinrin rere, awon elewonyi ni ati mu awon mo kuro ni bi isokuso, ti won un so won, ti won ni aforijin, ati arisiki ti o ni aponle”. (Suratu Nuur: 26) .

Amoo Eyi ti o sokale, nitori tie ti osi je, idajo fun gbogbo Musulumi: Ohun naa ni, aaya imora oni iyepe (al-ttayammum), ti o je ike ati irorun, fun gbogbo ijo Anabi.

Imam Al- Bukhary ati Muslim gba oro wa, lati odo A’aisha oso bayi pe: “Ohun ya egba orun kan, lowo Asmaahu, ni oba sonu, Ojise Olohun wa ran awon saahbe re, pe ki won lo wa egba naa,

[1] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (4786).

akoko irun si to ba won ni be, won wa ki irun naa, lai se aluwala, nigba ti won pada, si odo anabi, won so un kan ti o sele fun, bayi ni aaya imora oni iyepe ba sokale. Usaid bin Hudair wa so wipe: ki Olohun san o ni esan rere, iwo (A'aisha) nitori pe, ohun ti ofe kan ko sele si o rii, ayafi ki Olohun se ona abayo fun o, kosi tun je oore ajenjetan (Alubarka) fun gbogbo Musulumi".[1]

7- Ini fe Anabi si gbigba itoju, ninu yara A'aisha, Anabi ku si igbaaya A'aisha, ni ojo ti pinpin orun kan, Olohun pa ito enu awon mejeji po, ni akoko ikanyin fun Anabi, lori le aiye, ti o si je ibere akoko asiko wi wo ile ikanyin, (al-qiyamat) won si sin Anabi, si inu iyara re. Imam Al- Bukhary gba oro wa, lati odo A'aisha oso wipe: "Abdurrahman ibn Abubakr wo ile to Anabi, pelu pako tutu lenu re, nigbat ti mo gbe Anabi, si igbaaya mi, Ojise Olohun wa bojuwo, pako naa, mo wa gba pako naa, mo wa je lenu kunna, leyin naa, mo wa fun Anabi, o wa run un….."[2]

8- Anabi fun wa ni Iro pe, A'aisha je ara aljannah.

Imam Bukhar gba oro wa, lati odo Qaasim bin Muhammad, pe: "A'isha un keta ero, Abdullah bin Abbaas wa wole wa ba, osi so fun wipe: Ire iya awon olugbagbo ododo, o un lo ba awon asiwaju ododo, bi Ojise Olohun ati Abibakr".[3] Ti obari bee, Abdullah ibn Abbaas ko ni so oro yii, a fi ki o je pelu, eri lati odo Anabi. Bakan naa ni Imam Al-Trimidh gba oro wa, ti Abdullah bin Ziyad al-Asady so wipe: "Mo gbo Ammaar, ti o un so wipe: A'isha je iyawo Anabi ni aiye, ati ni orun".[4]

---

[1] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (3773).

[2] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (4438).

[3] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (3771).

[4] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (3772), ati Jaamihu Al-Trmidh, ounka hadith je (3889).

9- A’aisha ni oni imo julo, laarin awon obinrin Musulumi, nitori pe ogba awon hadith, ti o le ni egberun meji wa, lati odo Anabi,[1] lafikun awon agbaagba sahabe, won a mo bere idajo esin ni owo re.

### 4) Ahfsat bint Umar bin al- Khattaab:

Iya awon Olugbagbo ododo Ahfsat bint Umar bin al-Khattaab ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Ahfsat bint Umar, bin al-Khattaab, Ohun ati Abdullah bin Umar, ni won jo je omo Baba kan naa, Iya re ni Zainab bint Mashu’n, omo iya Uthman bin Mashu’n, bin Habib bin Wahab bin Hudhafa, Ojise Olohun fe, ni Odun keta leyin ijirah, leyin oko re Khanis bin Hudhafa Albadary, ti o ku si Madinah, Ahfsat je eni ti o maa un gba awe gan, ti o si mo un yan nofila pupo, Won bi iya wa Ahfsat, ni igba ti o ku odun marun, ti Olohun yio gbe Anabi dide ni Ojise, o si ku ni osu Sha’ban, odun karunlelogoji leyin Hijra.

**Ninu awon Aponle re:**

1- Ori agbega latari sise Hijirah, pelu oko re, Ibn Sa’d gba oro wa, lati odo Abil- Huwairith, ti o so bayi pe: “Khanis bin Hudhafa fe Ahfsat bint U’mar,[2] won si jo se hijrah lo si Madinah.[3]

2- O mo un gba awe gan, o si maa un yan nofila pupo, o si tu je iyawo Anabi ninu aljannah.

Imam Al- Ttobaraani gba oro wa, lati odo Qais bin Zaid, ti o so bayi pe: “Ojise Olohun ko Ahfsat sile ni ekan,...Ni igba ti Anabi, wa wo ile si odo re, o fa Jalibabu re bo oju, Ojise Olohun wa so pe: Jibreel ki Olohun ke, so wipe: Gbaa pada nitori o mo un gba

---

[1] A’aisha gba ahdith (2210) wa, ohun ni eni ikerin ti ahdith re poju leyin Abu Hurayrah, Abdul-Lah bin Umar, ati Anas bin Maalik, ki Olohun yonu si gbogbo won. Lowo Asmahu al-saahba al-rruwaat, titi ibn Azim, oju ewe (39), ati Taliqihu fuhuumi aali al-athar ti ibn al-Jawzy, oju ewe (363).

[2] Oko re je ninu awon eni akoko ti won se hijrah, osi wa si ogun badar, leyin ti oti hijra delati Ahbashat, osi wa si ogun uhud, ibe si ni won ti sa ni ogbe ti opo, eyi lofi ku si ilu Medinah. Al-Istiia’ab titi ibn Abdul- Barr (1\134) ati al- isaabat titi ibn Ahjar (2\345).

[3] Al- Ttabaqaat al-kubra, titi ibn Sa'd (8\18).

awe gan, o si maa un yan nofila pupo, o si tun je iyawo re, ninu Aljannah.[1]

3- Ni gba ti won ko Al-quran jo, ni asiko Abubakr, Oda abo bo si odo re, titi ti o fi ku, leyin iku abu bakr, obo si odo U'mar, ni akoko arole re, leyin naa, obo si odo Ahfsat, won wa gbaa ni odo re, lati fi se akojo, eyi ti won se, ni igba Khalifa U'thman, won si daa pada si odo re, o wa wa lodo re, titi ti o fi jade ni aiye, ni odun ikarunlelogoji ni ilu Madina.[2]

## 5) Zainab bint Khuzima:

Iya awon Olugbagbo ododo Zainab bint Khuzima bin Abdullah ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Zainab bint Khuzaima, bin Abdullah bin A'mur, bin Abd manaf bin Hilal, bin Aa'mir bin Saa'saa' al-Hilaaliyyah, adape re ni, (Ummu al-Masaakikin) Iya awon mekunu, tori pe o mo un fun, awon alai koni ni ounje, o si mo un se saara fun won, Oko re tii se Abdullah bin Jahas ku, si oju ogun Huud, (Shahidi) leyin naa ni, Ojise Olohun fi se aya, Ojise Olohun wole too, leyin iya wa Ahfsat, ko si semi ni odo Anabi ju, osu meji tabi meta lo, ti ofi ku ni odun kerin leyin Hijra.

### Ninu awon aponle re:

O ti to ni iyi fun iya wa Zainab, lati mo be ninu awon iyawo Anabi, ati kiki irun Anabi si lara, ni igba ti o ku, eleyi je adayanri fun, nitoripe ko si eni, ti o ku ninu awon iyawo Anabi, loju aiye re, ayafi iya wa Khadija, ati Zainab, kiki irun si ni lara Ojise Olohun, si je ike fun gbogbo olugbagbo ododo.

## 6) Ummu Salama Hind bint Abi Umayya:

Iya awon Olugbagbo ododo Ummu Salama bint Abi Umayya ki Olohun yonu sii:

[1] Al-Mu'jam al-kabeer,18,365, ounka ahdith je (934) ati al-mustadrak ounka ahdith je (6753) al-silisilat al-ssahiah titi Albaany ounka ahdith je (2007) ati sahihi al-jamihi al-sagir wazyadaatih ounka ahdith je (4351).

[2] Sahihu bin Hibban (4506).

Oruko re ni Ummu Salama, Hind bint Abi Umayya, (Uthifah) Al-Mkhazumiyya, ara iran Quraishy, adape baba re ni, Eseunpa fun awon arin-irin-ajo, (zaadul-Rakib) nitori ore re, eni ti oba baa rin, irin ajo, ko ni bukta lati mu un kan kan lowo, Oruko iya re ni A'atika bint A'amir, ebi Kinaniyah lat inu awon omo Firaas. Ojise Olohun fe, leyin iku oko re, tiise Abi Salama bin Abdul-Asad, ti o je omo aburo baba re lokunrin,[1] eyi ti ose hijrah pelu re lo si Habasha, leyin naa won tun lo si Madina, Ummu Salama je, obinrin akoko, ti o gun esin wo ilu Madina, o si je arewa obinrin, ti o ni aponle ninu ebi.

**Ninu awon aponle re:**

1- Anabi fi se aya, o si tun se adua fun. Imam Muslimu gba oro wa, lati odo Ummu Salama, ti o so bayi pe: “Ojise Olohun ran Ahatib bin Abi Baltaa' pe, ohun fe fe mi, mo wa so wipe: mo ni omobinrin, ati wipe mo je ojowu, Ojise Olohun wa so wipe: ohun yi o bee Olohun pe, ki oroo loro tayo omobinrin re, ohun yio si tun bee OLohun, ki o mu owu jije re, kuro fun”.[2]

2- Ojise Olohun fun wa ni iro pe, yio je ara alijanna. Imam Ahmad gba oro wa, lati odo Ummu salama, ti o so bayi pe: “Anabi da aso gbagere dudu bo, A'li, ati Faatima, ati Hasan ati Husain, ki Olohun yonu si won lapapo, o wa so wipe: Ire Olohun ma se ina ni ile fun mi ati awon ara ile mi, Ummu Salama wa so wipe: ati emi naa ire ojise Olohun, Anabi wa so wipe: ati iwo naa”.[3]

3- O je ojogbon, oni laakaye ti o peye, ti o ni opolo pipe, Olohun se ogbon re ni, ona abayo fun awon sahabe, kuro ni ibi itapa si ase Ojise Olohun, eleyi han ni ojo Hudaibiya, ni igba ti Ojise Olohun pa, awon sahabe lase, ti o so fun won bayi pe: “Eyin eniyan, e pa eran idaya yin, ki esi fa irun ori yin, kosi eni ti oda lohun ninu won, otun tun so, kosi eni ti oda lohun ninu won, otun tun so kosi eni ti oda lohun ninu won, Ojise Olohun wa pada wole lo ba, Ummu Salama, osi so fun pe: Ire Ummu Salama: “kini o sele si awon eniyan”? O daun pe: Ire Ojise

---

[1] Ohun bakan naa ni otunje omo aburo baba Anabi lobinrin, iya re ni Umymat bint A'bdl-Muttalib.

[2] Sahihi Muslim, ounka ahdith je (918).

[3] Musnad Ahmad (6\296, 6\304) ounka ahdith je (26582). Ninu egba wa miran, lati odo Umar bin Abi Salama, eni ti Anabi gba to oso un be bayi pe: “Ummu Salama so pe, emi naa un be pelu won, ire Ojise Olohun, Anabi wa so pe: Ire un be ni aye re, ire un be losi ibi rere” (Imam al-Trimidh, ounka ahdith je (3812). Ahdith yi fi iyi Ummu Salama han.

Olohun, oti de si won, ohun ti o ri un, Mo ba won so oro kankan, iwo saa lo si idi eran idaya re, ki o du, ki o si fa irun ori re, ti o bati se bee, logan ni awon eniyan naa, yio bere si mo se bee, Ojise Olohun wa jade, ko ba enikankan so oro, olo si ibi ti eran re wa, osi du, leyin eyi osi fa irun ori re, bayi ni awon sahabe naa bere, sini pa eran won, won si tun un fa irun ori won. Olugba oro wa so pe: laarin ilu Makka si Madina, ni Olohun so ogba oro (Suratul Fatihi) kale.[1]

Igba Anabi ni imoran re yii, un toka sii, pipe laakaye re, ati sise anfaani ogbon re.

## 7) Zainab bint Jaahsh:

Iya awon olugbagbo ododo Zainab bint Jaahsh ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Zainab bint Jaahsh, bin Riahb, bin ya'mur al-asadiy, ore awon idile A'bdu Shams, oje okan ninu awon obinrin akoko, ti won se hijrah, oruko iya re ni, Umymat bint A'bdul-muttalib, bin Ahshim, aburo baba anabi lobinrin, anabi fi se aya, leyin odun keta tabi odun karun, leyin ti oti un je aya, ni odo Zaid bin Ahrithah, omo odo anabi, eyi ti awon eniyan un pe ni, omo anabi. Ifi se aya yii je, lati fi se alaye idajo, iyawo eni ti awon eniyan, un pe ni omo eni, ti kosi ri be. Anabi fi Zaid bin Ahrithah se omo, ki olohun to gbe dide, gege bi anabi, eyi ni idi, ti awon eniyan fi un pe ni, Zaid ibn Muahmmad, Olohun Oba wa fe pa ohun ti won un so yii re, lati se alaye pe, Zaid kii se omo Muhammad, pelu gbolohun Olohun ti oso wipe: "Emaa fi oruko baba won pe won, eyi ni se dede ju lodo Olohun" (Suratul-Ahzaab: 5).

Bakan naa, lati se alaye siwaju, fun ikan pa mo idajo yii, Olohun se ni ofin pe, ki Anabi fe iyawo Zaid bin Ahrithah,[2] ki ole baaje mimo, fun awon eniyan pe, Zaid kii se omo bibi inu Anabi, aayat sokale bayi pe: "…Nigba ti Zaidu ti pari bukata re, ni odo re, ase ni iyawo fun o…" (Suratul- Ahzaab: 5). Zainab je okan, ninu awon asiwaju lobinrin nipa esin, asaje ati ore tita, ohun naa si ni akoko, eni ti oku ninu awon iyawo anabi, leyin ti anabi ku tan, iku re si je ogun odun leyin Hijrah.

---

[1] Lowo egba wa yi ni pipe ninu Musnad Ahmad bin Hanbal (4\323).

[2] Lowo tafseer ibn Katheer, suratul-ahzaab, aayat (37).

**Ninu awon aponle re:**

1- Olohun Oba fi fun anabi gege bi aya, lati oke sanmon meje meje. Olohun so pe: “Atipe ki ose iranti, nigba ti ire un so fun, eni ti Olohun se ore fun, ti iwo naa si tun se ore fun pe, mu iyawo re dani shinshin, ki osi beru Olohun, ati pe ire (Anabi) un fi pamo, si inu okan re, ohun ti Olohun yio se afiahn re, o wa un beru awon eniyan, be si ni Olohun ni oto pe, ki o beru re ju, nigba ti Zaidu ti pari bukata re ni odo re, A see ni iyawo fun o, nitoripe ki oma ba je laifi, fun awon olugbagbo ododo, nipa fife iyawo omo ti won npe mo ara won (ti oti koo sile) ni gba ti oba ti pari bukata tie pelu re, ase Olhun je ohun ti oni lati se” (Suratul- Ahzaab: 37).

   Zainab naa ama se iyanran, lori awon iyawo Anabi toku, ama so bayi pe: Awon ara ile yin, ni won fi yin fun Anabi, sugbon Olohun ni oso oyigi temi fun Anabi, lati oke sanmo mejeeje.[1]

2- Fifi Zainab bint Jahash, se aya fun Anabi je, okun un fa ti ayah iboju fi sokale: Imam Al-Bukhary gba oro wa, lati odo Anas bin Maalik, oso bayi pe: “Nigba ti won fi Zainab tore fun Ojise Olohun, ti osi wole too, Anabi se ounje osipe awon eniyan, leyin ti won jeun tan, won bere si ni mo takuro so, Anabi un wole osi unn jade si won pada, won kosi parade, ni Olohun ba so aayah kale bayi pe: “Eyin ti egba Olhun gbo ni ododo, ema se wo awon ile Anabi, afi ti won ba yoda fun yin, lati jeun lai koje wipe, e un reti ki ojina, sugbon nigbati aba pe yin, e wole, nigbati eba jeun tan etuka, ki esi matun joko, lati ma soro (leyin ounje) Dajudaju eyi je inira fun Anabi, sugbon o un tiju fun yin ni, atipe Olohun Oba kii tiju nipa (siso) otito, atipe nigbati eba fe toro nkan lowo won, (awon iyawo anabi) ebere lowo won leyin gaga, eyi je afomo julo fun okan yin, ati fun okan awon naa, ko to fun yin ki ese ohun ti yio je inira fun ojise Olohun, atipe eko gbodo fe awon iyawo re leyin re lailai, dajudaju eyi je nkan ti o tobi lodo Olhun” (Suratul- Ahzaab: 53). Bayi ni won da gaga sile, awon eniyan si dide wo un lo.[2]

---

[1] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (7420).

[2] Sahihi Al-Bukhary, ounka ahdith je (4792).

3- Anabi yin laarin awon iyawo re, latari itore anu ati inawo re, si oju ona Olohun. Imam Muslim gba oro wa, lati odo A'aisha oso bayi pe: "Anabi sope: "Eni ti yio koko wa bami, leyin iku mi, ninu yin, ohun naa ni, eni ti oba le tore ju lo, laarin yin, A'aisah sope: awon iyawo anabi, untore gan lati mo, eni ti ore re poju laarin won, eni ti oje olore ju laarin wa, ni Zainab, nitori wipe o un fi owo re se ise, osi un se itore aanu pupo".[1]

4- Ninu awon ajulo re ni, ohun ti A'aisha so bayi pe: "Mikori obinrin kan, ti oni ore ju ni esin, ti osi ni ipaya olohun ju, ti osi so ododo ju, ti osi ro ebi re po ju, ti osi po ni itore anu, ti osi nipon ju, lati fi emi ara re tore, si ibi ise ni oju ona Olohun, lati fi ise naa sunmo Olohun, to Zainab bint Jahsh.[2]

### 8) Juwayriyat bint Al-Ahrith:

Iya awon olugbagbo ododo Juwayriyat bint Al-Ahrith ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Juwayriyat bint Al-Ahrith, bin Dirar bin Ahbib, bin Khuzaymah Al-khuzaiyyah, Al-mustalaqiyyah. Won mu ni eru ni ogun banil- mustalaq, (Al-muraysyhi),[3] ni odun ikarun, tabi ikefa leyin hijrah, won si pin fun Thaabit bin Qays, osi ko iwe fun lati tu sile, leyin ti oba san, owo itu eru sile tan, Anabi si ba san owo naa, osi fi se aya, leyin ti oti koko je iyawo lodo, Musafihi bin Safwan, eyi ti won pa si ogun naa, latari pe anabi fi se aya, awon Muslim (olugbagbo ododo), won tu awon ogorun si le, ninu awon eniyan Juwayriyah, (alubarika) tobi pupo fun awon eniyan re, oku ni aadota odun leyin hijrah.

### Ninu awon apanle re:

1- Opo ni ijosin gan, osi mo un ranti Olohun lopolopo: Imam Muslim gba oro wa, lati odo A'bdul-Lah bin A'bbas, lati odo Juwyriyah, wipe: "Anabi fii si aye ibu kiru re, lowuro kutu ti un ranti Olohun, leyin ti oti ki iru asuba tan, Anabi tun pada wa ba ni aye naa, lakoko iyaleta, lori isesi ti ofi si, Anabi wa so wipe osi un be lori isesi yii naa? Osi fun lesi pe: bee ni, Anabi wa so

---

[1] Sahihi Muslim, ounka ahdith je (2452).

[2] Sahihi Muslim, ounka ahdith je (2422).

[3] Oje oruko fun kanunga fun awon Khuza'h, eyi ti owa laarin Makkah si Madinah.

wipe: Motiso oro merin kan leyin re, ni igba meta, ti won ba gbe si, ori osun won, yio tewon ju ohun ti oti unso lati owuro lo, oro naa ni yii: Subuahnal-Lah wabi ahmudihi a'dada khaliqihi waridoh nafsihi wazinat a'rishhi wamidada kalimatihi.[1]

2- Anabi tun oruko re so ni Juwayriyah, leyin ti oruko un je Barrah,[2] eyi je apanle fun, gege bi oti se je bee, fun Maymunah bint Al-ahrith, eyi ti alaye re un bo.

### 9) Ummu Ahbibah Ramulat bint Abi Sufyan:

Iya awon olugbagbo ododo Ummu Ahbibah Ramulat bint Abi Sufyan ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Ummu Ahbibah, Ramulat bint Abi Sufyan, Sakhar bin Ahrib bin Umayyah, bin A'budi Shams, Al-umawiyyah, Iya re ni Safiyyah bint Abi Al-a'si, bin Umayyah, won bi ni odun iketadinlogun, si waju ki won to gbe Anabi dide ni ojise, osi gba esin Islam, pelu oko re, Ubaydul-Lah bin Jaahsh al-asadiy, awon mejeji si se Hijrah, losi Ahbasah, ibe losi bi omo re Ahbibah sii, osi gba esin re mu sikun, sugbon oko re pada di elesin kiriyo,[3] Olohun wa fi oko miran, eyi ti oni ore juulo paro fuun, ohun naa ni Ojise olohun. Ummu Salamat si ni iran re sun mon Anabi julo, laarin awon iyawo re, osi ba Anabi tan lodo, baba agba A'bud Manafi, Oku ni odun kerinlelogoji leyin Hijrah.

**Ninu awon aponle re ni:**

1- Ise apanle ite Anabi, latari pe oko fun baba re, ti oje osebo, lati joko le lori, nigba ti baba re wa si odo Anabi, fun atunse laarin awon Muslim ati Quraysh.

2- Ose Hijrah elekeji losi Ahbashah.[4]

### 10) Safiyyah bint Uyay bin Akhatab:

---

[1] Sahihi Muslim, ounka ahdith je (2726).

[2] Ojise Olohun ama yi awon oruko, ti o un toka si ifo ara eni mo pada, si oruko miran, lati fi mu oro Olohun se, eyi ti oso pe: "Nitorina ema se maa fo ara yin mo, Olohun lomoju nipa eniti o un paya re" (suratun- Najmi: 32).

[3] Ori esin kiriyo si ni Ubaidul-Lah bin Jaahsh ku si, ki Olohun so wa kuro nibi ipari buruku, ohun nikan ni eni ti oku si ori esin miran, ninu awon omo iya Zainab bint jaahsh.

[4] Anabi si gbe ori yin fun, awon ti won se hijrah losi Ahbasha, ose hijrah meji otooto fun won. Lowo: Sahihi Muslim, ounka ahdith je (2502).

Iya awon olugbagbo ododo Safiyyah bint Uyay bin Akhatab ki Olohun yonu sii:

Oruko re ni Safiyyah bint Uyay, bin Akhatab bin sa'yah, lati idile bani al-nadiir, osi je ninu omo omo Laawi bin Ya'quub, aromo domo Aarun bin Imran, okoko je iyawo lodo Salam bin Mishkam, ki otogba Islam, leyin re Kinanah bin Abil- Uqyq, naa tun fe gege bi aya, sugbon won pa oko re yii, ni ogun Khaibar, won si mu Safyyah ni eru, won si pin fun Duhuyat Al-kalby, osi ko iwe fun lati tu sile, leyin ti oba san owo iso eru di omo tan, Anabi si ba san owo naa, osi fi se aya, owa fi itu okun eru lorun re, se owo ori re (sadaqi), oku ni odun kejileniaadota leyin hijrah.

## Ninu awon aponle re ni:

1- Oje iyawo Anabi, otunje omo obinrin Anabi, gege bi aburo baba re, naa ti seje Anabi: Imam Trimidhy gba oro wa, lati odo Anas, ki Olohun yonu sii, oso bayi pe: "Iro kan Safiyyah wipe, Afsah so bayi pe: omo juu ni, leyi ti ofi eleyi bu, bayi ni Saffiyyah un sun eku, Anabi wole too, osi baa lori ise si yii, obere lowo re bayi pe, kini oun pa o lekun, ofun ni esi wipe, Ahfsah soro bayi nipa mi, Anabi wa so bayi fun wipe: omo obinrin Anabi ni o, aburo baba re naa, si tun je Anabi, gege bi otun se un be, labe Anabi gege bi Aya, ki wani Ahfsa un se iyanran, lori re si, leyin naa ni Anabi wa so fun Ahfsa, bayi pe: beru Olohun Oba re."[1] [2]

2- Anabi fi ododo royin re, nigba ti oso fun Anabi, lori aare re bayi pe: "Mobura pelu Oruko Olohun, ire Anabi Olohun, mosi gba ero koja si wipe, ohun to un se o emi ni un se."[3]

## 11) Maymuunah bint Al- Arith:

Iya awon olugbagbo ododo Maymuunah bint Al- Arith ki Olohun yonu sii

Oruko re ni Maymuunah bint Al- Arith, bin Ahzan bin A'amir, bin Sa'sa'h Al-ilaliyyah, Iya re ni Hind bint A'wf, oko re

---

[1] Jaamiu al-trimidhy, ounka ahdith je (3892).

[2] Itumo eyi ni pe, baba re je Ahroon, aburo baba re je Anabi Musa, ire naa si tun je iyawo mi. Ninu tira imam trimidhy (3892), Anabi so fun Safiyyat un be bayi pe: "O wa so fun ni wipe: bawo ni ose lore ju emi lo, Muahmmad si ni oko mi, baba mi si ni Ahroon, aburo baba mi si je Musa".

[3] Musannaf Abdur-Razzaq (431\11) ounka (20922), ati Tabaqaat ibn sa'd (128\8).

akoko ni, Mashud bin A'wf al-thaqafiy, leyin re ni, Abu Rahm bin A'budl- Uzzah naa tun fe, sugbon oko re yii ku, A'bbas ti oje alamojuto re,[1] wa fi fun Anabi, gege bi aya, Anabi si wole to gege bi iyawo, ni saraf eba Ilu Makkah, ohun naa ni obinrin ti, Anabi fe gbeyin, ni odun ikeje, ni gba ti ohun lo san umurah pada.

**Ninu awon apanle re:**

1- Anabi jeri wipe onigbagbo ododo ni: A'budl-Lah ibn A'bbas, gba oro wa bayi pe: Anabi so bayi wipe: "Awon omo iya lobinrin kan je, olugbagbo ododo, Maymunah iyawo Anabi, anti re tii se Ummul-fadhil bintl- ahrith, anti re tii se Salmah bint al-arith, iyawo Ahmuzah, ati Asmahu bint Umays, ti gbogbo won je, omo iya kan naa."[2]

2- Anabi tun oruko re so ni Maymunah, leyin ti oruko un je Barrah, Imaml- Ahkim gba oro wa, lati odo A'budl-Lah bin A'bbas, oso bayi pe: "Oruko aburo iyami lobinrin un je Barrah, Anabi wa tun so ni Maymunah."3 Eyi je apanle fun, gege bi oti se je bee fun, Juwayriyah bint Al-ahrith, gege bi alaye re, ti se gba waju tele.

---

[1] A'bbas bin A'bdul-Muttlib je, oko omo iya re lobinrin, tii se Ummu l-Fadili bint Al-Ahrith, fun idi eyi, Maymuunat un je aburo iya lobinrin fun A'bdullah bin A'bbas. Ki Olohun yonu si gbogbo won lapapo.

[2] Al-Mustadrak, (33-32\4), Sahihu al-Jamihi al-Sageer, (2763), ati Silisilat al-aahdith al-sahiah, (1764).

[3] Adith yi wa ninu tira, Sahihi Muslim, lati odo Abi Urayrah, (2141), ati ninu Mustadrak al-Ahkim (30\4), ninu awon ahdith ibn A'bbas.

# Ipe ni si esin ninu isemi awon iya awon olugbagbo ododo

Ipe ni si esin je ero Pataki, fun awon iya awon olugbagbo ododo, ki olohun oba yonu si won lapapo, eyi keyi oro Anabi, ti won ba so fun won, tabi ti won ba gbo, fun rara won, won yio tara sasa, lati se alaye re fun elomiran, gege bi Anabi se so pe: “Ki Olohun se idekun re, fun omoniyan kan, ti ogbo orowa, ti osi mu oro naa de etigbo elomiran, melo melo eni ti ogbo oro, ti yio si muulo ju, eni ti osoo fun lo.”[1]

Awon iyawo Anabi dayato, si awon obinrin miran, pelu igbaaye imo, ati agboye esin, awon ijo Anabi ko, opolopo awon idajo esin lowo won, eyi ti o un wulo, fun awon eniyan lapapo, awon iwe akosile itan esin, ti se alaye, ipa ti won ko, ni abala biba eni so oro olohun Oba, ati ipa eni lase sise dada, ati kiko fun eni, kuro nibi iwa ibaje. A o ti so asoju, ti aba wipe, Khadijah ni eni akoko ipile ise takun takun, ti opile ise, ipe eni si esin, titi ti esin fi ni ikesejari, ni ibere pepe esin Islam. Nitori pe ohun ni, akoko eni ti ogba Ojise Olohun gbo lobinrin, ti osi fi owo ati emi re, ran esin lowo, oje iyawo rere, eyi ti oki Anabi laya, ti osi gba eko esin lodo re, ni igba ti wahayi sese bere, lati odo Olohun. Anabi so nipa re bayi pe: “Ogba mi gbo, nigba ti awon eniyan un ko, ise ti Olohun fi ran mi si won, osi tun gba mi ni olododo, nigba ti awon eniyan, un pe mi ni opuro, ofi owo re se mi ni oore, nigba ti awon eniyan, un se owo won ni ewo fun mi”[2]. Khadjah ko ipa Pataki, lati polongo esin olohun, ki Olohun yonu sii.

Bakan naa ni A’aishat bint abu Bakir, je eni ti o hah, opolopo awon ahdith Anabi, lati polongo re, laarin awon eniyan, awon oni mimo, ati awon alagboye wa un ko imo lodo re, awon eniyan ti opo si gba, awon idajo esin, ati eko esin lopolopo, lati odo re, ti won fi un so bayi wipe: Dajudaju, ida kan ida merin idajo esin, wa lati odo re. Awon ijo Anabi, ati awon ti won tele won, se eyin ti opo, fun A’aishat ati imo re. Masruuq so bayi wipe: “Mori awon abewu lori, agba gba ninu awon sahabe Anabi, ti won un bi A’aishah leere,

---

[1] Sahihu al-Jamihi al-Sageer, ounka ahdith (6764).

[2] Al-istiia’ab titi ibn A’budl-Barr (589\1).

nipa imo ogun pinpin". Masruuq a tun mo so nipa re bayi pe: "Olododo tiise omo obinrin olododo, ololufe eni tiise ololufe olohun, eni ti olohun fo mo, lati oke sanmo mejeje, bami soro, miko si je pee niro."[1] A'tah bin abi Rabah so bayi pe: "A'aishat je eni ti oni agboye julo, ti osi ni imo julo, eni ti opolo re to, lati mo se dede oro, laarin awujo lapapo."[2] Hisham bin Urwah gba oro wa, lati odo baba re, ti oso bayi pe: "Mikori enikan kan, ti oni ebun imo agboye esin, imo iwosan, ati imo orin kiko, to A'aishah."[3] A'budullah bin Ubaid bin Umair, so bayi pe: "Enikan koni kedun lori A'aisha, ayafi eni ti oba je iya fun."[4]

Ninu awon ona ipeni si esin re, nii o un ti owa bayi pe: "Ahfsah bint A'bdurrahman, bin abi bakr, wole to A'aishat, ti osi fi ibori felefele bo ori re, eyi ti un fi orun re han sita, A'aishah si fa ibori naa ya, owa so fun bayi pe: "owa mo o un ti Olohun so kale, ninu suratu nuur ni? Leyin naa owa fi ibori miran, boo lori pada."[5]

Bakan naa ni, Zainab bint Jaahsh, ki olohun yonu sii, oje oni mimo ti un fi ima naa sise, ti osi je eni ti un se ikilo, fun gbogbo olugbagbo ododo, lokunrin ati lobinrin, lati lo sunna Anabi, ni oju aiye re ati leyin iku re, oda abo bo igboran re, ati iri ran re, kuro ni ibi o un ti Olohun binu si. Nigba ti Anabi bi lere nipa, o un tori si iro, ti won pa mo A'aishah, oso bayi pe: "Moda abo bo igboran mi, ati iri ran mi, miko mo oun kankan nipa re, ayafi dada".

Bakan naa ni Maymuunah bint Al-Ahrith, gba opolopo awon ahdith wa, eyi ti oso po mo awon idajo agboye esin, apejuwe eleyi ni, o un ti o sele, ni ojo a'rafah, nigba ti awon eniyan un se, iye meji nipa pe, se Anabi un gba awe tabi kogbaa ni a'rafah, Maymunah fi wara ranse sii, ni aye naa, osi muu loju gbogbo awon eniyan.[6] Bakan naa ni pe, ogba wa alaye iroyin, bi Anabi se un we iwe janabah.[7] Gege bi, oti se je oni ikilo, fun gbogbo awon ijo pata pata,

---

[1] Siyar A'alaam al-Nnubala (181\2).

[2] Al-mustadrak, (6748), Al-istiia'ab, (1883\4).

[3] Al-istiia'ab, (1883\4).

[4] Siyar A'alaam al-Nnubala (185\2).

[5] Al- Tabaqaat al-kuburah, titi ibn sa'd (72\8).

[6] Sahihu Muslim ounka ahdith je (1989).

[7] Sahihu Muslim ounka ahdith je (317).

ki olohun yonu sii, ati gbogbo awon iya awon olugbagbo ododo lapapo.

## Idaruko awon iya awon olugbagbo ododo labala bi won se gba hadith Anabi wa si [1]

1- **Olododo omo olododo, (A'aishat) ki olohun yonu sii:** ahdith togba wa je, egberun meji, ogorun meji, ati mewa (2210) ogorun kan ati merinlelaadorin ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary ati Muslim, (174) Merinlelaadota ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhari nikan, (54). Mesan si wa ninu tira, Imam Muslim nikan, (9). Imam Ahmad gba ahdith A'aishat wa, ninu Musnad re, eyi ti o le ni egberun meji.

2- **Ummu Salamah ki olohun yonu sii:** ahdith togba wa je, ogorum meta, ati mejidinlogorin (378), gege bi Imam Al-Dhaaby se gbaa wa. Metala ninu re, wa ninu tira Imaml-bukhari ati Muslim, (13). Meta pere ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary nikan (3), nigba ti metala wa, ninu tira Imam Muslim nikan. (13).

3- **Maymuunat bint Al-Ahrith, ki olohun yonu sii:** Imam Al-Dhaaby sope: ahdith to gba wa je, metala, (13), meje ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary ati Muslim, (7), okan soso ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary nikan (1), nigba ti marun, wa ninu tira Imam Muslim nikan. (5).

Shaykh Irfan al-a'sha, so payi pe: ahdith togba wa, po juu eleyi lo, nitoripe imam Ahmad gba ahdith re, wa ninu tira re, tii se Al-Musnad, ahdith re bere ninu tira naa, pelu ounka (10\26858), osi pari si ounka (10\26921).

Ninu tira (Asma'h Al-saahbah Al-rruwat) owa nibe bayipe: ahdith to gba wa je, merindinlogorin (76), oni gege tira naa, gba oro Kuahlah wa, ti oso ninu tira (A'alaam Al-nisah) bayi pe: Ninu tira (Matolihu al-aniwaar) owa nibe bayi pe: ahdith ti o gba wa je, metadinlogorin, (77), bakan naa ninu tira (Al-kamal fi ma'rifat Al-rijal) owa ni be bayi pe: ahdith to gba wa je, merindinlaadota (46). Ninu akojopo awon tira, (Dar al-kutubi al-

[1] Lati le se alaye, awon egba wa adith, awon iya awon olugbagbo ododo, ki Olohun yonu si won, a o gba wa lati inu tira marun, awon tira naa ni: Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, Siyar Aa'laam al-nubala, titi Shamusu al-ddeen al-Dhaby, ati Makhatuu' titi Baqiyu bin Mukhalad al-Andalusy, ati ktaabu al-nnsai fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha ahsunat al-dmashiqy.

sahiriyyah) owa ni be bayi pe: ahdith to gba wa je, mokandinlogorin (79).[1]

4- **Ummu Ahbibat bint abi sufyan, ki olohun yonu sii:** Ninu tira (Asma'h Al-saahbah Al-rruwat) owa ni be bayi pe: hadith togba wa je, marunlelogota, (65), bayi naa ni ibn Al-jaoziy so ninu tira re, tii se (Talqeehi Fuhuml- Athar).[2] Eyi naa ni, Al-imam Al-Dhaby so wipe: ahdith ti o gba wa je, marunlelogota,[3] (65), meji ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary ati Muslim, nigbati imam Muslim da meji gba wa, ninu tira re.

5- **Afsah bint Umar bin Al-khattab, ki olohun yonu sii:** Imam bin Ahzim, so bayi ninu tira, (Asma'h Al-saahbah Al-rruwat) pe: ahdith ti o gba wa je, ogota (60), bayi naa ni ibn Al-jaoziy so, ninu tira re, tii se (Talqeehi Fuhuml- Al-athar)[4]. Al-imam Al-Dhaby so bayi pe: "Ahdith ti o gba wa ninu tira, Baqyi bin Mukhalid je, ogota, (60)."[5] Merin ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary ati Muslim, nigbati imam Muslim da mefa gba wa, ninu re. Shaykh Irfan Al-A'sha, so payi pe: ahdith ti o gba wa, ninu tira al-musnad, ti oje ti imam Ahmad, apapo re je, merinlelogoji (44), obere ni ori ounka (26485) titi de ounka (10\26529).[6]

6- **Zainab bint jaahsh, ki olohun yonu sii:** Imam bin Ahzim[7] ati Imam ibn Al-jaozy,[8] so bayi pe: ahdith ti o gba wa je makanla, (11). Shaykh Irfan al-a'sha, so payi pe: ahdith ti o gba wa, ninu tira Al-musnad, ti ti Imam Ahmad, obere lati ounka (10\26813-26816) ati ounka (10\27483- 27486). Imam Al-Trimidhy gba ahdith wa fun, ni ounka (2187), Imam bin Abi Shaybah, gba ahdith wa fun, ni ounka (19061), Imam ibn Hibban naa, gba ahdith wa fun, ni ounka (827), bakan naa ni, Imam Al-Bayahqiy,

---

[1] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (68).

[2] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (72), Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (365).

[3] Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha, oju ewe (208).

[4] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (75), Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (365).

[5] Siyar Aa'laam al-nubala, titi Shamusu al-ddeen al-Dhaby, oju ewe (230-227\2).

[6] Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha, oju ewe (124).

[7] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (153).

[8] Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (369).

gba hadith wa fun, ninu al-sunan al-kuburah, ni ounka (10\93), bayi naa ni al-imam Al-Bagawiy gba hadith wa fun, ninu Sharihu al-sunnah, ni ounka (4201), ati awon elomiran.[1] Bayi naa ni imam Malik, gba hadith wa fun, ninu tira re Al-muattah ni ounka (1268), bakan naa imam Al-Nnasahi gba, hadith re wa, ni ounka (3500).[2]

7- **Safiyyah bint Uyay bin Akhatab, ki olohun yonu sii:** Imam bin ahzim[3] ati Imam ibn Al-Jaoziy[4] so bayi pe: ahdith ti o gba wa je, mewa (10), bayi naa ni Al-imam Al-Dhaby so, osi fikun wipe: eyokan soso ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary ati Muslim,[5] eyi ti o wa lodo Imaml-Bukhary je, ounka (2035), nigbati ti Imam Muslim je, ounka (2175), atipe eyi ti Imam Ahmad, si gba wa je, (10\26927) ati (10\26929).[6]

8- **Juwairiyat bint Al-ahrith bin Abi dirar, ki olohun yonu sii:** Imam bin Ahzim[7] ati Imam ibn Al-Jaoziy[8] so bayi pe: ahdith ti o o gba wa je, meje, (7), bayi naa ni Al-imam Al-Dhaby so, osi fikun wipe: eyokan ninu re, wa ninu tira Imaml-Bukhary, nigbati meji ninu re, wa ninu tira Al-imam Muslim,[9] Shaykh Irfan al-A'sha, fi kun payi pe: ahdith ti o gba wa lodo, Al-imam Ahmad ninu Al-musnad je, ounka (10\26820-26817), osi un be ninu akojopo yii, eyi ti o yato si, eyi ti ati daruko si waju.[10]

9- **Saodat bint Zamua't, ki olohun yonu sii:** Imam bin Ahzim[11] ati Imam ibn Al-Jaoziy[12] so bayi pe: ahdith ti o gba wa je, marun (5), eyi ti o wa ninu tira Imaml-Bukhari je ounka (6686,6749), nigbati ti eyi ti o wa ninu tira Imaml-Muslim je ounka, (1457), ti

---

[1] Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha, oju ewe (186).

[2] Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha, oju ewe (186).

[3] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (155).

[4] Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (369).

[5] Siyar Aa'laam al-nubala, titi Shamusu al-ddeen al-Dhaby, oju ewe (238 \2).

[6] Shykh al-A'sha ni o se alaye yi ninu tira re, Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, oju ewe (239).

[7] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (371).

[8] Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (371).

[9] Siyar Aa'laam al-nubala, titi Shamusu al-ddeen al-Dhaby, oju ewe (263 \2).

[10] Nisaau fi dhilli Rasuli al-Lah, titi Shykh Irfaan Al-A'sha, oju ewe (200).

[11] Asmahu al- Saahbah al-ruwaat, titi ibn Ahzm, oju ewe (222).

[12] Taliqiihu fuhuum aahli al-athar, titi ibn al-Jawzy, oju ewe (372).

inu tira imam Ahmad si je (10\27488), (10\27487), (10\27489) (2\ 6127) nigbati imam Al-Nasaahi gba hadith re wa, pelu ounka (3485).

Sugbon Khadijah bint Khuwaylid, ati Zainab bint Khuzaimah, kosi ahdith kan, ti awon mejeji gba wa, ki olohun yonu sii gbogbo won lapapo.

Eyi ni ororun fun wa, lati kojo ninu awon egbawa, ahdith awon iya, awon olugbagbo ododo, ki olohun yonu si gbogbo won. Lati fi se alaye ipa takun takun ti won ko, lati polongo ahdith anabi, ki ike ati ola olohun ki o maba.

## Oro ipari

Eyi ni akojo po, awon ajulo awon, iya awon olugbagbo ododo, eto ni ki agbamu, gege bi ipese, lati fi ma se, alaye nipa awon oro ibaje, ti awon eniyan un so, nipa won, ni ada yanri, ati nipa awon ara ile anabi lapapo.

Latari idi eyi, odi oro yan lori, awon iyawo ati awon omo wa, ki won ko awon iwa won yii, ki won si mulo, ki won si tun fi ko awon eniyan, ninu ile won, ki won leje ikose rere, ati apejuwe dada fun elomiran, bayi ni ao se lee so, apakan ninu awon iwo, awon iya awon olugbagbo ododo, lati se apanle, ibowo, igbenitobi fun won, ki asi je ki oje mimo wipe, sise apanle anabi naa ni, sise apanle awon iyawo re.

## Awon iwe iseri si

1- Al-stiia’ab Ibin A’bdl-Barr Al-andalusiy. Daarl-ihlaam (ounte akoko) Al-Urdun 2002.

2- Al-bidaayat wal-Niahyaht Ibn Katheer, Al-Ddimashqiy taba’t al-ma'arif, byrooty.

3- Zawjaatul- Nabiyy fi waqihina al-mua’sir, Jaasim al-Mutwwa’h (ounte akoko) Al-Kuwait- 2001.

4- Sunan Al-Trmidhiy- Daars-Salam- Al-Riyad-2000.

5- Siyar Aa’laaml-Nubalah, al- Dhabiy, matiba’at muassasat al-isalah, Ikokanla, taqeeq Shuaib Al-Arnauut.

6- Sahihi ibn Hibban, taba’t alr-Risaalah, byroot.

7- Sahihi Al-Bukhariy, Dar as-Salam- 2000.

8- Sahihi Al-jaamihi al-Sageer waziyadatihi, Al-Albaaniy al-maktab Al-Islamiy.

9- Sahihi Muslim- Al-Imam Muslim- taba’t Dar Al-Salam- 2000, Al-Riyad.

10- Al-Ttabaqaat Al-Kuburah, ibn Sa'd, taba’t Sadr- Byroot.

11- Mujammah Al-Zawahid- Al-Ahythamiy, taba’t Al-Fikir-Byroot-2141.

12- Musnadl- Imam Ahmad bin Ahnbal, taba’t qurtabah- Al-Qahirah- taqeeq Shuaib Al-Arnauut.

13- Muhujamu- al-Tabaraniy Al-Kabeer- Abul- Qasim Al-Tabaraniy- maktabatul- huluum wal-hikam- almusal- taqeeq Ahmadiy al-salafiy-4041.